# Eto itoju ti fun Alaboyun



Itosona lekun rere

Ile ise NHS ti Greater Glasgow & Clyde se ileri lati se itoju ti o peye fun alaboyun ati pe a si ni lati ri pe gbogbo eni ti o wa si odo wa fun itoju ri itoju ti o peye ni ona ti o to pelu owo.

E ni awon eto nigbati e ba n lo ile ise wa.
Bi apere, enikeni ko ni eto lati fi eebu eleyemeya bu yin tabi ba yin lo pelu iyasoto odi lona ti ko to.
E si tun ni eto si iranlowo ominira ti o yato si ti ijoba fun apere lati odo awon ile ise ti o n se aanu mekunu fun itoju ti o tun peye si .

Eto itosona lesese wa yio se alaye gbogbo ipele oyun lati ibere titi di eyin ibimo. Etoyinsi ogbufo tio peyefun i tojuko gbeyin peluawon nomba ti a le llo fun ogbufo a ti bi a se le lo won .

## Igbese1

## Fi oruko sile fun itoju alaboyun

Se ipinu lati ri agbebi ki e si fi oruko sile lati ri agbebi ni kete ti e ba ti mope e feraku.

A ro eyin iya ti e nreti omo fun igba akoko ati eyin ti e ti bimori ri o wa ninu oyun lati fi oruko sile lati ri awon agbebi ti o wa nitosi yin larin ose kefa(6) si ose kewa (10) ti e loyun.

O se koko lati tete se awon ayewo ti o ye lati mo ipo ti omo wa paapaa fun ilera iya omo naa ni igba ti oyun yi sese duro lara ke e si ri wipe e n lo pade awon osise ile iwosan nigba kugba ti win
ni ki e wa ki e si ma pa ikankan je ninu ipade yin pelu won. Awon agbebi yi o fi oye ye yin lori bi ouhn gbogbo se nlo lori oro oloyun de , won o si so fun yin ti e ba nilo itoju si ti o koja itoju ti e ti n rigba tele lo.

Nomba yi ni e ma pe lai mu ojo ti won ma ri yin ati lati fi oruko sile
0141 347 8422

e le se amulo ogbufo ori ero ibanisoro wa lati pe ipe yi.

E ni eto lati beere fun ogbufo lowo okan ninu awon osise wa fun gbogbo igba ti e ba wa fun eto itoju .

## Igbese2

## Lilo si ipade pelu awon osise iwosan

Laarin igba ti e ba wa ni ipo iloyun, e o ri awon agbebi kan si meji lati ba soro ki e ba le mope oro yin je won logun paapaa julo kii se pe orisirisi enian otooto ni yio ma bayin soro. E ni eto lati beere ibeere ti o ba wu yin, lori ohun kohun ti ko ye yin.

Ni ipade akoko pelu agbebi, a o ni ki eni ti e jo wa tabi olubase yin se gafara ki agbebi le bere ibeere ikoko ni owo yin fun iseju perete. Eyi je ohun ti gbogbo alaboyun yio la koja
Itoju yin le je ibi ti o sunmo ile yin. Ti e ba wa lori iranwo ijoba, e le gba owo oko ti o gbe yin wa pada, e si le yege fun awon iranlowo ijoba bi Best Start Grant, Best Start Foods tabi the Scottish Child Payment. Eyin e sa ti bere lowo osise wa.

E ri daju pe e so fun agbebi ti e ba
ni idojuko lori ati de ipade ni ile iwosan
E ni eto si alaye ni ede ti o ba wu yin paapaaa julo be e se le toju oyun, ati awon ayewo ti o peye pelu ipalemo fun ibi. Pelupelu, gbigbaradi fun itoju omo ati awon orisi ounje ti o wa fun omo ni jije. gbogbo nkan wonyi ni agbebi yin yio ba yin so ,ti e ba si ri wipe e o ti alaye ti o peye gba lori awon nkan wonyi, e ma sai ba okan ninu awon osise wa soro lati salaye fun yin daradara.

## Igbese3

# Eko fun Alaboyun

Awon eko yi se koko lati gbaradi fun irobi ati ibimo,paapaa julo ouhn ti e ma ni lo lati bo omo yin ti e ba bi ati lati toju ara yin

E le beere fun ogbufo lati joko ti yin ni awon akoko eko wonyi
Eni ti yio se ogbufo yi yio joko si egbe yin yio si ma fi jelenke ma tumo re fun yin pelupelu lati ba yin beere ibeere ti e ba ni.

Eyin ati olubase yin le jo wa si awon ipade yi. Awon na yio gba eko ati imoran lati ran yin lowo lati akoko iloyun , ti irobi ati ibimo. Won yio si tun keko pelu lori ona ati se itoju omo titun. Alaye lori ifi eto si omo bibi wa leyin ibimo pelu.

## Igbese4

# Gbigbaradi fun ibimo

O pon dandan lati ba agbebi re soro lori igbaradi lati bimo, paapaa julo eni ti e fe ki o wa pelu yin ni akoko irobi ati ibimo., e si tun le soro lori ona igba bimo bi, ibimo sinu omi, ibimo sinu ile, eto ati dekun irora, ounje ati paapaa Ogbufo

Awon osise le ma le tele eto ibimo ti e fi sile nitori oro ilera tabi ailera amo won yio salaye fun yin bi o ba se je. A le ran yin lowo lati bere irobi (ti e ba nilo re gege bi eto ilera). Awon elo miran le nilo ise abe lati bimo. Awon agbebi yio salaye eyi ti o ye yin fun yin paapaa julo ti e ba ni ibeere.

## Igbese5

# Ibimo

Opolopo obirin lo gbero lati bi omo won si ile iwosan. Ti e ba ti kefin pe e n robi e yara pe ile iwosan ti e fi oruko le si –

Princess Royal Maternity Hospital
0141 201 3453/3454

Queen Elizabeth Maternity Hospital
0141 232 4363

Royal Alexandra Community
Maternity Unit
0141 314 7033

Royal Alexandra Maternity Unit
Labour Ward
0141 314 6067

Vale of Leven Community
Maternity Unit 8am-8pm*
01389 817232

Inverclyde Community
Maternity Unit 8am-8pm*
01475 504619

*Ni akoko ti ko si ise e pe Royal Alexandra Hospital Labour room lori 0141 314 7033

Agbebi kan yio ba yin soro lori ohun ti o n sele yio si so ohun ti o kan lati se.
E si le lo eto ogbufo ori ero ibanisoro wa pelu.

Bi e ba n robi lowo, e ni eto lati se ipinu lori ohun
gbogbo ti e n se paapaa eto didekun irora. Ti e ba ri wipe eto idekun irora yi ko muna doko, e so
fun osise wa imiran ti o ba wu yin

E si tun le beere fun iranwo ogbufo pelu ni igba irobi

## Igbese6

# Itoju leyin ibimo

ti e ba wa ni ile iwosan leyin ibi e ni eto si iranwo ogbufo ti e ba n baa won agbebi ati awon dokita soro nipa ijiroro lori oro ilera ati i toju.

E gbodo ri atileyin lati fun omo lohunje tabi lati toju ara yin ni ona ti o wu yin.
Ti e ba ti de ile, agbebi yio wa ma be yin wo fun igba melo kan titi di ojo mewa (10) leyin ti e bimo. Alejo ilera yio wa ma be eyin ati omo naa wo lati ojo kokanla (11) si ikerinla (14).

Won yio si tun ma be yin wo nigba oyun miran lati ri wipe ohun gbogbo nlo dede. Alejo ilera yin yio so fun yin nipa oun bi abere ajesara ati awon ibi ti e o ti ma gba won fun omo.
Won si tun le se eto iranwo ogbufo ni awon akoko ibewo wonyi.

**Lo iṣẹ itumọ tẹlifoonu wa lati ṣe ipe si eyikeyi iṣẹ NHS.**

**Foonu** 01413196131
O yoo beere fun nọmba PIN alaisan rẹ. Eyi jẹ ọdun 182987.
Iwọ yoo wa ni asopọ si onitumọ ni diẹ bi awọn aaya 15.
Sọ fun onitumọ nọmba ti o fẹ pe, fun apẹẹrẹ 0141 347 8422

(Ifowosi ọmọ iya)

O le lo iṣẹ yii lati pe eyikeyi awọn iṣẹ wa, pẹlu NHS24 (111) ati Awọn iṣẹ pajawiri (999).

**O ni ẹtọ si onitumọ fun gbogbo awọn ipinnu lati pade rẹ.**

Jẹ ki ọmọ ẹgbẹ oṣiṣẹ mọ boya o fẹ atilẹyin itumọ ni awọn ipinnu lati pade rẹ. Eyi le jẹ onitumọ oju si oju tabi iṣẹ itumọ tẹlifoonu wa.

Ti o ba nlo onitumọ oju si oju, o le beere ni pataki fun obinrin tabi onitumọ ọkunrin, ṣugbọn wọn le ma wa nigbagbogbo nitoribẹẹ ti o ba ni ayanfẹ to lagbara fun eyi o le nilo lati duro pẹ diẹ.
Jọwọ ṣe akiyesi pe ilana NHSGGC ni lati lo awọn onitumọ ọjọgbọn lati ṣe atilẹyin fun ọ pẹlu itọju rẹ, kii ṣe awọn ọmọ ẹgbẹ ẹbi tabi awọn ọrẹ.

**Kini lati ṣe ti o ba fẹ kerora nipa itọju rẹ**

Imọran Alaisan ati Iṣẹ Atilẹyin le ṣe iranlọwọ fun ọ lati fun esi tabi awọn asọye, gbe awọn ifiyesi dide, tabi ṣe awọn ẹdun ọkan nipa itọju ti o gba lati ọdọ NHS.
Kan si wa lori 0800 917 2127. O le lo wa iṣẹ pe yii.



## Kini ki e se ni igba pajawiri

Bi e ba se akiyesi pe eje nda loju ara yin tabi e se akiyesi pe e ni irora ni abenu tabi abenu ndun yin Eyi ko tumo si pe oyun yi ti fe jabo lara yin; kii se oun titun lati ri eje diedie ni oju ara ni ose 12(mejila) akoko ninu oyun. E yi ni a ma n pe ni threatened miscarriage.
Opolop o obirin man pada ni oyun aseyege leyin eyi awon kan si ma npadanu oyun won leyin eyi bakana.

Bi oyun yin ko bai ti pe ose Mejila (12) ti e si ni irora labenu tabi ti eje nyo loju ara yin
E yara lo si eka Accident and Emergency ti o sunmo yin julo.

E ri wipe e o losi Eka Pajawiri wa tabi ki e pe Oko Alaisan wa lori (999) ti e ba rip e -

- Irora Abenu yi po gidigidi (o si le je apa kan abenu yin)
- e ni irora ejika
- eje nda lara yi ju ti tele lo (eje didi njade lara yin tabi paadi yin n rin laarin 30 iseju)
- e n daku tabi subu lojiji

Ni akoko pajawiri, e le se imulo eto ogbufo ori ero ibanisoro lati ba awon osise wa soro ei ti won yio se eto re fun yin.

Ti Oyun yin ba ti koja ose mejila (12) ti e si nri eje tabi irora tabi awon aami ti adaruko tele, e jowo e tete pe eka ti o moju to alaboyun ni ile iwosan ti e ti fi oruko sile gege bi alaboyun fun amoran siwaju si

| | |
|---|---|
| Queen Elizabeth University Hospital | **0141 232 4363** |
| Princess Royal Maternity Hospital | **0141 211 3453/3454** |
| Royal Alexandra Hospital | **0141 314 6067** |
| Vale of Leven Hospital 8am-8pm* | **01389 817 411** |
| Inverclyde Royal Hospital 8am-8pm* | **01475 504 619** |

*Akoko ti ko si ise
Royal Alexandra Hospital on **0141 314 6067**

E le lo eto ogbufo ori ero ibanisoro Pelu gbogbo nomba ti a ko soke yi.